# KOKORO ASIRI



## (IWE ASIRI IJINLE OMO ODUDUWA TI O JE TI AWON BABA - WA)



Scanned with CamScanner

## (1) AROBI GIDI TI OGUN, ASASI, EPE KO FI NI RAN WA

Afatan irun ori eni, eekanna owo ati tese meweewa, imi eni die, ito eni die, ito enu wa die, ori ijapa kan, iye akala kan, odidi atare kan. Ao jo won papo, ao lo, ao ro sinu igo funfun kekere kan, ao wa lo ri mo eti odo nibiti yio ti maa tutu, eti odo nla ni o, wallahi kosi asasi, abilu tabi epe ti o le ran wa mo ninu aye.

## (2) AKOYA GIDI TI OTA WA YIO FI KU IKU GBIGBONA LARIN OJO MEJE

Ti a ba nsare owo ti a nsare ki aye wa o dara, ki a ma gbagbe lati sare emi gigun naa, k iota wa o ma se wa lori. Apa Atelewo kan ki ka ile, apa atelese ki ka ona, apa awonriwon kii ka igi oko, oro oloro lobi ku si, ori oro wa ni ota wa yio ku le lori Ase. E dan ise kekere yi wo, wallahi o daju gidi gan.

E loora Adieyan gidi, ki e da sinu ike iwe, ki e bu omi to to sanra leekan sii, ki e wa fi Ada ti o mu daradara sinu re lati ago marun irole titi di ale ojo naa, e o ni jade mo lojo naa o, e o lo fi omi naa sanra lale ojo naa, sugbon e ko gbodo nu omi naa kuro lara yin, ti o ba gbe mo wa lara tan, A o fi ada naa sibi igberi wa, ao maa gborile mole, wallahi iku gbona nisu nku, ada ni won yio fi pa ota wa ti o nsare emi wa, o daju ko le koja ojo meje.



Scanned with CamScanner

## (3) EYONU TO DAJU GIDI

Irawe igbo, irawe odan, eetan eyin, ewe ooyo, ewe sinkinmini, iseta ologede die, Ao lo won papo daradara ti yio kunna, ao wa da sinu ipara ti o ba wuwa ti o je funfun, ao da epo pupa die si, ao da ori die si, ao da Adieyan die si, Ao wa gbe sinu oorun ti gbogbo re ma yo papo. Ao maa fi para ti a ba we tan.

**Ofo re niyi:** Irawe igbo kii je ki iya o jegbo,
Irawe odan kii je ki iya o jeodan.
Bepo ba foju kan oorun a yo, bori ba foju kan oorun a yo,
Badi ba foju kan oorun a yo,
Komo araye yonu simi, ki won se mi lore.

## (4) OSE ASINA GIDI TO DAJU

Ao loo ja ewe ogbo tutu mejo, ao lo kuna daradara lori olo, ao lo kafura pelebe original odidi kan mo, ao wa po ose to ba wu wa mo, ao ko sinu ike kan, ao bere wiwe re ni ojo aje, wallahi o daju.

## (5) OSE ASIRIBIBO GIDI

Ori oka kan, ori ere kan, ori eye osin kan, owo osi eran iki, egbo igi nla, egbo gbogbonse, odidi eye etu kan, awo ekun die, iye agbe mewa, iye aluko mewa, ikode gidi mewa, ewe aje lopolopo, ewe orijin



Scanned with CamScanner

lopolopo, ewe etu lopolopo, eyele funfun meji, erupe okun, erupe osa, itun, ifa, abere lopolopo, ose dudu oni N1,000, ao ko gbogbo re sinu odo, ao gbe aje olokun ti o ho leti daradara kan le mole, Ao gun gbogbo re papo, ao po mo ose, Ao wa ko sinu awo funfun olomori kan, Ao pa eran obuko kan, Ao fi bo ose yi. Ao gbe ose yi sinu Apoti kan, emeji losu ni ao maa we ose yi o, Aso funfun (white) ni a gbodo maa fi bora lati igbati a ba ti nwe ose yi, ori kan ni ise yi wulo fun o. Obinrin ko gbodo de ibiti a gbe si o.

## (6) IFERAN OMO ARAYE

Ori eyele funfun, ori Akuko Adie, Oga ibile kan, ewe abamoda, ewe akinsanmi, eran elede, ewe ojusaju, odidi atare kan, oruka iyekiye, ao ko ewe abamoda tele ape, ao wa ko ori eyele ati ti akuko le lori. Ao wa ko oruka le lori, ao ko awon ewe ti o ku le lori, Ao wa fi ewe abamoda bo labotan, ao jo nigbati o ba jo tan, ao fi igi yo awon oruka naa, ao ko sinu igo, a o po ebu re mo ose, ao ma fi we lojojumo, ao ma fi oruka sowo nigbagbogbo.

## (7) AGBELE POTA GIDI

Ti ota ba po ni ki a to se ise yi o, nitori pe o lagbara gidi. Ese osi Adie, ao jo pelu odidi atare kan, ao fi sin gbere mesan tabi meje sori wa. Ti ori ba nfo wa, ao ra odidi agbon kan, ao fo, ao fi omi re fo ori wa, o tan.



Scanned with CamScanner

## (8) OSE ASIRIBIBO FUN INAWO

Egbo tude, eepo obo, eeru Alamo, eeru awonka, ao gun lotooto, ao wa po mo ose dudu, ao da ose naa si meta, ose ti a ba fewe lakoko ao fi ori para ki a to we, nigbati a ba we tan, ao lo ju ori toku seku sorita, ao so wipe eyin to laye, ori yin re o, e je ki asiri mi o bo nibi inawo ti mo fe se yi o. Ao tun fi epo pupa para ti a ba fe we elekeji, nigbati a ba we tan, ao tun lo ta epo pupa sorita, nigbati a ba fe we eleketa, ao fi oyin ogidi para ki a to we, ao tun loo ta oyin sorita nigbati a ba we tan. Wallahi, asiri yio bo.

## (9) OSE AWURE EYONU

Ao bu iyo tele inu igba, ao jo eyin ororo meta si, Ao da epo pupa si, Ao da oyin igan ogidi si, Ao wa fowo wa po ose dudu mo ninu igba yi, idi igba yi ko gbodo kanle mo. Ao maa bu we ni gbogbo igba.

## (10) OSOLE ASIRIBIBO

Eyin pepeye nla meta, Rasu to fe die, odidi atare meta, ewe onitikuti pupo, Ao jo papo, a o da sona meta, ao fi oti stout lo eyo kokan fun odidi ojo meta leralera. O daju wipe Asiri yio maa bo.

## (11) ASINA GIDI

Ori Aparo ti ese re wa lenu re, odidi atare kan, afara oyin, ao jo papo, ao lo kunna, A o da sinu igo to



Scanned with CamScanner

gbowo, Ao waa jo eyin eyele meji, ati eyin adie ororo kan si, ao tu oyin ogidi le lori, ao ma la lowuro pelu adura.

## (12) AGBO AROMOLEGUN GIDI

Omi osan wewe, ito maalu, alubosa elewe, iseta ologede, ewe taba tutu, eeru Alamo. Ao se lagbo, yio ma mu ni gbigbona.

## (13) ASIRI BIBO TO DAJU GIDI

Eyele funfun ojuda, eso laa pupa ati funfun, ori oka to lase lenu, odidi atare kan, Sise re: Ao yo epa inu awon eso laa mejeeji, ao ko epo re danu, ao pa eyele yi sinu isasun tuntun, ao la aya re, ao fi ori oka sinu re ati odidi atare kan, ao gbe sinu isasun, ao waa da epa inu eso laa mejeeji le lori, ao jo, nigbati a ba jo tan, ao lo kunna, ao ro sinu ado kan, idi re ko gbodo kanle o. Ao maa fi oti Schnap lo lago kan oru nihoho pelu adura oun ti a nfe.

## (14) ASIRI BIBO OLOTI

Odidi okan malu ti ko womi, ewe onitikuti agolo kan, N1,000 tuntun, Ao la okan malu ti ko womi, Ao ki owo si ninu, Ao da ewe onitikuti le lori, Ao tu oti Schnap igo kan le lori, Ao jo. A ko gbodo si wo, ao lo kuna nigbati a ba jo tan, ao ro sinu oti Schnap miran, ao tu miliki olope meta si, ao maa muu.



Scanned with CamScanner

## (15) AWURE ENITI O NWA ALAANU

Obo ewure, ewe atewogbare, ewe ido ati ina re, ewe sinkinmini, ewe omisinmisin mejeeji, ao gun papo mo ose dudu. A o maa fi we.

## (16) AWURE BASIRI KIAKIA

Ako Alangba kan, Ao ko owo eyo ti ko luju kekeke mesan si lenu, abo alangba, ao ko owo eyo ti ko luju meje si lenu, Ao ko won sinu fitila oloju merindinlogun, Ao fi odidi atare kan si, Ao waa ko ewe onitikuti le lori ti yio bo tan, ao jo, Ao fi miliki olope lo leekanna.

## (17) AWENU GIDI

Ipepe irin alagbede, ewe orijin tutu, ao gun won papo mo ose, ao maa bu we diedie, lagbara Olorun gbogbo owo buruku to ba wa lara ni yio kuro.

## (18) AWURE OSOLE TO DAJU

Ewe abamoda 32, Ao ko 16 sinu isasun tuntun, Ao ko oga ibile gbigbe merindinlogun (16) le lori ati atare odidi merindinlogun (16) le lori. Ao wa ko ewe abamoda merindinlogun (16) toku le lori, ao jo po, ao da si ona merindinlogun (16), ao fi oti Schnap lo fun ojo merindinlogun (16), ko gbodo din ojo kan o, ise yi daju sugbon o dara ki won o ba wa se ni ka ma se funra wa o.



Scanned with CamScanner

## (19) AWURE ASINA

Owo eyo ti ko luju mokanla, Ao lo, Ao da sinu N20 tuntun, Ao di bi tira, a o wa ki bo enu opolo ijokun laaye, Ao gbe sinu isasun tuntun, A o fi odidi atare kan si, A o jo po, A o fi miliki olope lo leekanna lale ojo ti a jo gangan.

## (20) EBE AWON AGBA GIDI TI WON FI NTUWO LORO ENIYAN

Awo lili to lori meta, eepo obo, igi nla, ewe afeloru to je toojo ti ko kanle, odidi atara kan, ao jo papo. Ao maa fi fo eko tutu mu.

## (21) EBU OSOLE

Oga aye to tobi daradara kan, ao fi eeru Alamo mesan si lenu, ao fi rasu die si, pelu ewe onitikuti, ao fi odidi atare kan si, A o jo po, ao lo kunna, Ao fi oti lo leekanna ni agogo kan oru (1.00am) pelu adura.

## (22) EBE AWON AGBA GIDI

Eyin Adie idaba meta, eku asin tutu ti won ko tu ifun re kan, oga ibile kan, A o ki ikode bo Asin ati oga naa lenu o, itanna ako ibepe to po, Atare odidi kan, Ao jo papo. A o maa fi epo pupa la ni alaale, ao ma fi fo eko mu ni araro. Ori kan lo nlo ise yi o.



Scanned with CamScanner

## (19) AWURE ASINA

Owo eyo ti ko luju mokanla, Ao lo, Ao da sinu N20 tuntun, Ao di bi tira, a o wa ki bo enu opolo ijokun laaye, Ao gbe sinu isasun tuntun, A o fi odidi atare kan si, A o jo po, A o fi miliki olope lo leekanna lale ojo ti a jo gangan.

## (20) EBE AWON AGBA GIDI TI WON FI NTUWO LORO ENIYAN

Awo lili to lori meta, eepo obo, igi nla, ewe afeloru to je toojo ti ko kanle, odidi atara kan, ao jo papo. Ao maa fi fo eko tutu mu.

## (21) EBU OSOLE

Oga aye to tobi daradara kan, ao fi eeru Alamo mesan si lenu, ao fi rasu die si, pelu ewe onitikuti, ao fi odidi atare kan si, A o jo po, ao lo kunna, Ao fi oti lo leekanna ni agogo kan oru (1.00am) pelu adura.

## (22) EBE AWON AGBA GIDI

Eyin Adie idaba meta, eku asin tutu ti won ko tu ifun re kan, oga ibile kan, A o ki ikode bo Asin ati oga naa lenu o, itanna ako ibepe to po, Atare odidi kan, Ao jo papo. A o maa fi epo pupa la ni alaale, ao ma fi fo eko mu ni araro. Ori kan lo nlo ise yi o.



Scanned with CamScanner

## (23) OSE AWURE

Ise yi dara fun awon to ntaja pelu awon agbasese. Ewe onitikuti lopolopo, ewe apada, opolo ijokun gidi kan, Ao gun papo mo ose aladi, Ao ko sinu awo tasa ti o ti nata daadaa, Ao tu oyin ogidi le lori, Ao maa bu we. Ise yi dara gan, sugbon a gbodo ri wipe ko si ide lara wa ki a to maa loo.

## (24) EYONU ASINA

Eku Asin meje, oga gbigbe meje, eyin ororo mokanla, odidi atare meje, ewe afeloru oojo, eso laa pupa, eyele funfun kan, Ao jo papo, ao maa fi ogere epo la ninu awo tasa lale ki a to sun.

## (25) OWO GIDI

Segisorun kan, Ao ko eyo atare meje ati iwerenjeje meje si ninu, Ao waa we lowu dudu ati funfun ti ko ni han rara, Ao pa eje akuko adie kan si lara, ao re sinu re di ojo keji, Ao sa ti yio gbe, Ao ran lodi awo dudu.

## (26) ATEPA GIDI

Eso ijan kan, Ao lo pelu eyo atare meje, Ao fi sin gbere yipo ese otun, Ao tun waa lo eso ijan keji pelu eyo atare meje. Ao fi sin gbere yipo ese wa osi, o pari.



Scanned with CamScanner

## (27) EYONU GIDI

Itanna ila, itanna imi esu, ewedu, Ao lo kunna daradara, Ao fi ori Amo po, ao maa fi pa idodo wa la aro.

## (28) MALU GIDI

Ti awon omo alaigboran ba yaju siwa, ise yi ni a fi nko won logbon. Ao wa edo okete tutu, Ao po mo ose daradara, ao maa fi ose yi we oju ibiti won tin a wa. Ero re niyi: Ao ju ose yi die sinu oti ogogoro fun yio mun

## (29) ATUDE AWON AGBA LARA

Eso iwerenjeje lopolopo, ata ijosi die, egbo tude, Ao lo kunna, ao fi omi idi igbin po ose re, ao ko sinu ikarahun igbin. Ao maa we ose yi sun ni alale pelu omi to lo wooro.

## (30) EBE AWON AGBA GIDI

Eepo obo lopolopo. Ako Alangba meta, ewe egele lopolopo, eyin ororo meta odidi atare meta, Ao jo papo, Ao lo kunna, a o ma fi ogere epo la ka to sun lalaale. Ako gbodo jade mo o.

## (31) OSE ASIRIBIBO (MANAKANTAN)

Opolo maalu ti won pa loojo ti ko womi, ewe rere mejeeji, ewe etiponola, Ao gun po mo ose, Ao maa fi oyin igan ogidi po ose yi, A o maa bu we diedie.



Scanned with CamScanner

## (32) OSE ATUDE ARAYE

Ao gun ewe tude tutu papo mo egbo tude tutu, Ao gun ti yio kuna daradra, Ao waa po mo ose aladi Ao waa mu opolo ijokun kan, ao ju sinu igba olomori kan, Ao ko ose yi le lori mole, lehin ojo keta, lao to maa we.

## (33) ASINA GIDI

Ti eda ba wa ninu isoro airina, airilo, Ao loo ra odidi agbon nla kan to lomi ninu daradara, Ao jo omi inu re sinu ike kan, Ao gbe sinu iri mojumo, Ao wa loo gbe nidaji kutukutu, ki a to soro si enikeni, ao fi ewe akoko mesan tutu sinu re, ti o ba se obinrin a o ko ewe akoko meje sinu re, Ao fi omi agbon naa gbo daradara.

**Ofo re niyi:** Gbogbo aye lo nsanu akoko, omo araye e wa sanu emi lagbaja omo lagbaja. Ao wa gbe omi agbon naa mu. Ekan lodun kan ni a nse o.

## (34) OGUN IDI YIYO

Okunrun nla ti o ba kako, Ao gbe sinu agbada, ti ko nit u, Ao fi nkan le lori pelu odidi atare kan, Ao jo papo, nigbati a ba jo tan, Ao bu die sinu Aso waji gidi yio fi ti sinu. O daju.



Scanned with CamScanner

## (35) OGUN ENITI NGBON LOWO ATI ESE

Ao lo ra eyele owewe ti ko ti gunye rara, ile aladi kan, ewe ailu lopolopo, Ao jo po, Ao lo kunna, Ao po ebu naa mo ori ati epo pupa, yio maa la, yio maa fi para.

## (36) ASEJE OSOLE OWO KIAKIA

Ewe iranje tutu, Ao lo pelu iyere, Ao fi se odidi Adie agbebo kan je, ao wa fi iyerosun te ifa irete alaje, irete otura, a o pe ofo re si, ao da si obe nạa, nigbati a ba sokale, idi obe yi ko gbodo kan ile o. Ao je obe yi ni idaji kutukutu ki a to soro si enikeni. Ao pe ifa re si, Ifa re niyi: Okanran ndagba, Adaagbandagba, ifa na omo olokun, orunmila na omo olodo, orunmila ni bi won ti e fo ikoko owo mole nile baba mi, emi lagbaja omo lagbaja yio lowo, emi lagbaja omo lagbaja yio la temi dandan, mola, mola, ni omode nke mojo, oju ki pon iranje ilu ko ma so bi okun, ko ma so bi ide, bi Adie ba tan ile yio ri ohun ti o nwa, ki emi lagbaja omo lagbaja ri iye owo bayibayi ni kiakia. Ao waa je obe na. O daju wipe asiri wa yio bo, bi eniyan ba je gbese, yio ri san.

## (37) IMULE AWON AGBA GIDI TI WON FI NSINA OWO FUNNI

Odidi Ako okete aye kan, Ao la inu re, Ao ko orogbo mokanla si, obi gbanja mokanla, odidi atare mokanla, Aso funfun opa kan, Ao ko gbogbo awon



Scanned with CamScanner

nkan yen, Ao fi abere ran pa, A o wa fi Aso funfun naa di bi igbati a ba di oku, Ao waa so ko si arin meji yara fun ojo meje, ti obinrin kan ko gbodo wonu yara naa, lehin ojo keje, Ao gbe sinu ape, o di jijo. Ao gbodo siwo ti yio fi jo tan o, ti o ba jo tan, Ao lo, ao ro sinu Ato, Ao maa fi epo pupa la ni alaale ninu awo tasa pelu aniyan owo ti a ba fe pelu Ogo Olorun yio ri be.
Ikilo: Eniti o fe lo ise yi ko ni yio se o, won gbodo ba se ni o, Ao ni nawo anadanu o.

## (38) OGUN GBARI

Eku Asin meje, oga gbigbe meje, orogbo meje, obi gidi meje, odidi atare meje, Ao lo gbogbo re ti yio kunna daradara, Ao wad a sinu isasun tuntun, Ao wa toju igbe Adie inu kuku, ati obuotoyo, Ao lo lubulubu, Ao da si tinu isasun, epo ati Adieyan ni a o fi se obe yi, yio maa fi je amala dudu, amala isu, lagbara Olorun Oba, ko ni gburo re mo.

## (39) OSE AWURE ASINA OLA

Iwo omo iya mi, ise yi daju gidi gan sugbon eniti yio lo gbodo se sara fun awon agba ki o si ri wipe oun we awenu gidi ki o to lo ise yi o, Ao ni nawo anadanu o.
Igo oyin gidi kan, igo oti jin kan, ewe Daji 201, ewe etiponola 201, oga aye kan, Ao ko ewe etiponola tele inu igba, ao fi oga aye le lori, Ao wa ko ewe daji le lori, Ao wa fi opolopo ose bo monu igba naa



Scanned with CamScanner

daradara, igba nla ni ao lo. Ao de, ao gbe sinu apo aso funfun, ao gbe pamo fun ojo merindinlogun (16 days). Lehin ojo naa Ao gbe kuro ninu aso naa, ki a to fi owo kan ose yi, ao bu oti mu, ao bu sori ose naa, Ao to oyin la, Ao bu sori ose na, Ao waa fi owo ro ose yi papo daradara, ao tun gbe pamo sinu aso funfun yi fun ojo mefa (6 days) lehin ojo kefa ni ao to maa fi ose yi we sugbon, gbogbo igba ti a ba fee we ose yi, Ao maa mun oti die, Ao maa la oyin, Ao si maa bu sori ose naa.

## (40) EBU ASINA OLORI

Omo olongbo to ti to eku pa, Ao le mole ti yio ku, Ao gbe sinu isasun tuntun, Ao ko iru wooro ti ko niyo le lori ti yio bo tan patapata, Ao waa ge tangiri to kawo daadaa kan, Ao ko le lori pelu odidi atare kan, Ao jo, Ao lo kunna, Ao waa po ebu yi mo ori, Ao maa fi mun eko gbigbona lararo.

## (41) IFOKOMUN EDA

Ao sun opolopo ikarahun igbin nina, Ao lo lubulubu, Ao wa lo opolopo atare papo mo, yio maa fi fokomu lararo.

## (42) ISOYE OMO ILEWE

Ao han “rabbi Zidni iliman 33 soju opon walaa, ao fi omi agbon fo, Ao ro sinu ike kan, Ao war a eja ojiji



Scanned with CamScanner

Aye ni o, Ao fi sinu isasun tutnun, Ao waa lo ewe oniyeye, ewe omo ati ewe iyeye kunna daadaa, Ao da si eja ojiji yi, Ao wa if omi hantu yi se eja ojiji yi ni aseje, wallahi ti a ba ri ise yi se, olubori ni omo yi yio maa je laarin awon akeko egbe re. Ori kan ni o nlo ise yi o.

## (43) OSE ONISE MESAN

Ako Alangba, Abo Alangba, Oobe meta, Isu ogirisako, esuru gudugudu, itanna ako ibepe, eso ibepe dudu kan, eyin adie idaba, eepo obo, igi nla, eeru Alamo, ewe aluki, Ao gun papo ti yio kunna daradara pelu ose aladi, Ao wa fi oyin gidi, Adieyan, ati ori po papo daradara. Ao ko sinu igba olomori, ao gbe pamo fun ojo mesan, Ao koko we fun ojo mesan leralera, lehin naa ao maa we lojo keta-keta.

## (44) ASINA GIDI

Ifun eku Asin tutu, panumo abo meta, panumo bomubomu meta, eyo atare meta, Ao lo paopo dada, Ao fi po ose iwe eemeta, ao we tele rawon fun ojo meta, lagbara Olorun ayipada gidi yio de.

## (45) EYONU ASINA TO DAJU

Ewe tannaposo ati eso re, Ao ko sinu igo nla kan, Abere eyo meje, A obo eepo re kuro, Ao ko sinu igo naa. Ao lo ileke itun ati ifa da si, Ao tu oti Schnap le lori, Ao ma mu diedie

## (46) EGBE GIDI

Lojo idagiri, Ao poora ni o. Akisa ori akitan die, Alangba Adaripon kan, atare aja kan, Ao ge ori, owo, ese ati iru re kuro, Ao wa fi atare aja kan si nikun, Ao waa fi akisa ori akitan naa we daada, Ao jo papo, Ao lo kunna, Ao fi sin gbere yipo orun owo mejeeji, Ao tun fi sin ikun wa yipo, Ao tun fi sin itan wa mejeeji yipo, Ao tun fi sin orun ese wa mejeeji yipo. Lagbara Olorun, ti ijamba kan ba sele, Ao poora nibe ni.

## (47) ASEJE BASIRI GIDI

Igbin apinnu nla kan, Ao ji lowuro kutukutu laisoro si enikeni. Ao lo sidi igi botuje funfun, Ao ja omunu re ti yio po laisoro si eniyan, Ao lo papo mo ata ijosin, Ao fi se igbin naa je leponiyo, Ao mu oti Schnap le lori. A ko gbodo soro si enikeni ki a to ja, ki a to se ati ki a to je.

## (48) EYONU ARAYE TO DAJU

Rasu die, epo obo die, Ao lo lotooto ti yio kunna dada, Ao waa da papo, Ao fi iyo po mo ose, Ao tun fi epo pupa po, Ao wa ko sinu igba onikoko. Ao maa we ni ago mejila oru.

**Ofo re niyi:** Agba ni ti, Agba nii si, Agba ni silekun fagba wole. Araye kan ko le tilekun, ko so pe ki ara orun o ma wole, nitoripe eedi kii di iyo ko ma dun lobe, komo araye o ma tilekun oore mo mi.

Scanned with CamScanner

## (49) ATUDE ABURU LARA

Asin tutu kan, ikode gidi kan, Atare kan, Ao fi ikode ha eku Asin naa lenu, Ao jo pelu odidi atare kan. Ao fi ito ti a to ni idaji lo ebu yi ki a to soro si enikeni.

## (50) EYONU ARAYE TO DAJU

Ako Alangba merindinlogun (16), omo ayo ti won nta lowolowo merindinlogun (16), Ao paaro e pada, Ao ko atare 16 tele ape titun ti a fe fi jo. Ao wa ki omo ayo kookan si enu ako alangba kookan, Ao ko won sori atare 16 naa, Ao waa ko ewe ewuro oojo bo mole patapata, o di jijo, idi re ko gbodo kanle mo, inu ape naa ni a o ti lo. Ao ro sinu Ato kan, Ao fi ikode di lenu.

Lilo re: Ti o ba di agogo kan oru, Ao pakaja aso funfun, Ao gbe Ado nab o sita, Ao fi ogere epo lo nita gbangba ninu awo tasa, bayi la o se maa lo.

## (51) OSOLE OWO GIDI

Ise yi yara mu owo wa dada, sugbon eniti yio lo ise yi ko gbodo se fun rare o, nitoripe o ni majemu. Olongbo dudu ti ko labawon rara, Ako okete aye nla kan.

**Sise re:** Ao ge ori Olongbo dudu yi sibi kan, Ao ge ese re mereerin sibi kan, Ao ge iru re danu, lehinnaa ao wa ge ori okete yi, ese re mererin ati ase iru okete yi, Ao waa la inu olongbo yi, Ao fi N1,000 tuntun tele inu olongbo naa, Ao ko ewe ela mokanlelogun (21) si

ati odidi atare kan, Ao wa ko ori okete naa, ese re mereerin ati ase iru re si inu okutu olongbo naa, Ao fi owu dudu ati funfun ranpa pelu abere otutu, Ao gbe ju sinu agbada, ao jo, A ko gbodo siwo ti yio fi jo tan, nigbati ina ba dun daadaa, Ao ta oti Schnap si lori ina, Ao tun ta oti yika aaro ti a fi njo. Ao ko okutu okete naa, ori olongbo ati ese re mereerin pelu iru re sinu Aso funfun, Ao lo ri mole sori akitan.

## (52) AWURE OWO TO DAJU

Irun ori were, owu ti o la ti ko la tan to hu sori akitan ori akuko adie, ori eyele ati ese re, ewe orijin, ewe ajeobale, odidi atare kan, ao jo won papo, Ao po mo ose dudu, Ao ko sinu igba ademu, kainkain tuntun ni a o maa fi we.

**Ofo re niyi:** Onakona ni emi lagbaja omo lagbaja fe ki owo gba de owo mi loni nitoripe onakona ni were ngba wolu, odun ki dun kowu ma la, eni eleni lonkole feyele, eyin araye e bami wa owo temi loni o.

A kii se ise yi funra eni o nitoripe o ni majemu o, A o ni fowo ara wa sera wa o.

## (53) OSHOLE GBEWA GIDI

Odidi igun kan to nifun, odidi Akala kan to nifun, ori oka kan to lase lenu, ori agilinti kan, ori Alegba kan, ori olongbo to nirun kan, Ao jo papo, Ao da si ona meji, Ao po idakan mo ose aladi, Ao tu lofinda

Danduala mefa si, Ao ko sinu igba Ademu, ikeji Ao maa fi oti Macdowel lo ti a ba de lati ile iwe.

## (54) EYONU AWON AGBA

Olongbo dudu ti ko lami Kankan, Ao gbe sinu agbada, Ao to akara elepo merindinlogun (16) yipo re, Ao waa ko opolopo ewe ajeobale ti ko kanle le lori monle, Ao jo pelu odidi atare kan, Ao maa fi ebu re fokomu tabi ki a ma fi Schnap lo ni alale ki a to sun.

## (55) ASINA OWO GIDI – MONEY DRAWING

Okete tutu ti won pa lojo, Ao ko ewe ewuro tele agbada, Ao gbe okete yi le lori, Ao ko ewe ewuro to ku bu mole, pelu odidi atare kan, ifokomu

## (56) EBE AWON AGBA GIDI

Eyele funfun ti ko lami rara, eepo jebo, eepo obo to po, tangiri eyo kan to kawo dada. Ao pa eyele yi, eje re ko gbodo kanle, inu ape ni a ro eje re si, Ao gbe eyele naa le mole, Ao maa ko awon eroja yooku le mole, ko ni atare ninu o. Ao maa fi ebu naa fokomu lale tabi laaro.

## (57) OSHOLE OWO GIDI

Oga ibile gbigbe meje, Awo lili to lori meje, iye agbe meje, iye aluko meje, ikode meje, odidi atarae meje,



Scanned with CamScanner

Ao maa ta Schnap si lori ina ti yio fi jo tan, Ao lo kunna, Ao ro sinu ato, Ao pa eyele funfun balau kan bo Ato yi, Ao maa fi oti Schnap lo lararo, o daju.

## (58) OGUN EBE ASINA OWO

Oronro malu mokanla, odidi atare mokanla, ewe akoko oojo. Gbogbo owo ti a naa. Ao jo po, Ao ro sinu Ato kan Ao maa fi fokomu lararo, Ao maa fi ogere epo lasun ni alale.

## (59) ATUWO, ATUDE GIDI

Ewe sawerepepe lopolopo, Ao sa ti yio gbe, ori Ako aja to nirun, igbin apinnu merin, eepo obo to finmu dada, Ao jo papo pelu odidi atare kan, Ao maa fi fokomu leekan losu kan.

## (60) ASINA OWO GIDI

Ako Alangba Aye marun, ori olongbo to nirun odidi atare kan, Ao ko ewe ewuro oojo le lori, Ao jo papo, Ao maa fi Schnap lo larolaro.

## (61) ARIMOLE AWORO

Ao ra isasun tuntun kan, Ao ko eyele ejigbede si ninu pelu ewe awoyoyo pelu odidi atare kan, Ao de pa, Ao we ni owu dudu ati funfun, Ao gbele lenu ona ibiti a fe ri ise yi mo, Ao gbe sinu ile ti a gbe, Ao wa ra sugar



Scanned with CamScanner

St. Louis pali kan, Ao ko le lori, Ao tu oyin igan ojuda gidi le lori pelu igo epo pupa kan. Ao sadura si daadaa, Ao wa erupe bo mole, Ao ni ki won o ba wa fi Cement re mole, o pari.

## (62) ISORI GIDI

Oogun yi je ti atijo ti awon baba baba wa nlo. Ni ojo idagiri, Ao poora ni o. O daju.

Akisa ori akitan, Alangba Adaripon kan, atare aja kan, Ao ge ori, owo, ese ati iru re kuro, Ao wa fi atare aja naa si nikun, Ao fi akisa ori akitan naa we daadaa, Ao fi sinu ape, ao jo, Ao sokale sori olo, Ao lo ti yio kunna dada, Ao fi ebu re sin gbere yipo orun owo mejeeji, Ao tun fi sin ikun wa yipo, Ao tun fi sin orun ese wa mejeeji yipo. O pari Lagbara Olorun ti ijamba ba de, Ao poora nibe ni.

## (63) ATUDE ARAYE LARA

Eepo obo die, egbo Asorin die, Aso awon agba die, Ao lo ti yio kunna dada, Ao waa la eku Asin tutu kan laya, Ao da etu naa si, Ao wa di pelu Aso pupa ti ko ni han rara, Ao tun wa fi owu dudu ati funfun di ni ikobere ti ko ni han rara, Ao ju sinu igba onikoko, Ao tu Adieyan le lori ti yio mu doke daadaa, ojo keta ni a to bere si lo diedie. Ale patapata lao maa lo o.



Scanned with CamScanner

## (64) ASEJE AWURE (IRETE ALAJE)

Akuko Adie funfun kan to ko jayejarun, ewe ina, ewe inabiri, ewe eesi, ewe aaragba, ewe oloyin, ata ijosin div, Ao lo papo. Ao fi se Akuko Adie yi laseje, leponiyo. Nigbati obe yi ba tutu, Ao fi iyerosun te ifa irete alaje iruekun, Ao gbadura edun okan wa si dada, Ao je tan patapata. Gbogbo egungun Adie yi, Ao jo pelu odidi atare kan, pelu awon ewe naa bakannaa, Ao ro sinu igo funfun, Ao maa fi oti Schnap lo lararo.

## (65) ONMO GIDI

Ewe omo gidi, ewe ojiji ti ko luju, edun gidi mefa, Ao lo awon ewe yi ti yio kunna papo mo edun mefeefa, Ao fi se okan aja ti won pa loojo laseje.

## (66) EBE AWON AGBA GIDI

Eyin Adie idaba meta, eku Asin tutu kan, Oga ibile kan, itanaa ako ibepe pupo, Atare odidi kan, Ao jo papo, Ao maa fi epo pupa la ni alale, Ao maa fi fokomu lararo.

## (67) ATUDE ASINA

Ao gba irun abe obinrin ti a ti ba sun ri, A o lo papo mo apaku eyin Adie, tewetegbo tude, ata ijosi 16, Ao po papo mo ose, Ao ko sinu fitila, Ao ma fi omigbona we sun lale.



Scanned with CamScanner

## (68) EYONU ASINA

Aidan onigun lopolopo, Oga ibile gbigbe kan, A o jo pelu odidi atare kan, Ao ma fomi lo pelu Adura.

## (69) OSE ITUWO ELEYE

Egbo tude, ota inu iroko, eepo obo, iwerenjeje, A o gun won kunna dada, Ao ra igbin nla kan, Ao je ki igbin yi rin, A o da etu die sile ninu eyiti a gun. Ao je ki igbin naa o fie nu ko die ninu etu naa, Ao po eyi toku mo ose dudu, Ao ko soju igbin naa, Ao maa we laro kutukutu.

## (70) ATEPA GIDI

Ewe alupaida eyo mesan, eyo atare mesan, imi olongbo Ao lo papo ti yio kuna daadaa, Ao fi sin gbere yipo orun ese wa mejeeji.



Scanned with CamScanner